# GBIGBANI NI IYANJU NIPA SISE AYEWO ARUN HIV.

**Kini gbigbani ni iyanju je ki a to se ayewo fun arun HIV?**

A ni lati se awon ayewo ki a to le mo boya eniyan ti ko kokoro HIV. Igbani ni iyanju je ona tuntun, ti o si ti fi idi mule ni opo awon ilu ni agbaye.

**Kini itumo aifi ipa mu ni ki a to se ayewo?**

Eyi tumo si wipe olukuluku ni eto lati pinnu lati se ayewo yi, tabi lati ko. Eni ti o ba ni ife si sise ayewo yi ni anfaani lati baa won agbani ni iyanju fi ikuluku ki a to se ayewo naa. Eniyan si ni eto lati ko ayewo, ni iwon igba ti iru eniyan bee ko ti se tan lati se ayewo naa.

**Ki ni idi ti a fi n se igbani ni iyanju ki a to se ayewo fun ni?**

E yi wa ki a fi ni idaniloju wipe ooye ayewo yi ye eniyan daadaa, bi a o se se ayewo naa, ati itumo esi ayewo pelu. Gbigbani ni iyanju a maa fun eniyan ni aaye lati bere awon ibeere ti o ro mo arun HIV ati iru ayewo ti a fe se. Ti eniyan ba ti se tan lati se ayewo yi lehin ti a ti se igbani ni iyanju, iru eni bee ni lati fi owo si iwe ki a to le se ayewo fun.

**Bawo ni ayewo se n sise?**

Ni kete ti kokoro HIV ba ti wo inu ara eniyan, ara iru eni bee a bere si ni mu awon ohun kan jade , eyi ti a le ri ti a ba se ayewo eje iru eni bee. Ayewo yi ko gba akoko rara, a si le ri esi ni nkan bi ogbon iseju.

**Ki ni o n sele ni igba ti a ba n se ayewo yi?**



Awon onisegun to kose mose lo n se ayewo yi. A maa n gba eje die lati omo ika tabi lati apa eniyan. Eje yi ni a maa n lo lati se ayewo naa. Ni igba miran a maa ni lati tun ayewo yi se, ti a o si ni lati tun gba eje miran lara eniyan bee.

**Se a le gba esi ayewo yi gbo?**

Esi ayewo yi se gbagbo, o si je eyi to funni ni idaniloju. O se se ki a tun ayewo yi se ni igba meji tabi ju bee lo lati fi idi esi naa mule sinsin.

Awon akoko kan wa ti a ko le gba esi ayewo naa gbo patapata:

1. Ti eniyan ba sese ko kokoro HIV, ni iwon bi ose meta si osu meta, ayewo yi ko ni le so pato ohun ti o n sele. Idi ni wipe ara iru eni bee le maa ti bere si ni gbe awon eroja ti a so oro re tele jade si inu eje.
2. Awon omo ti iya won ti ni kokoro yi a maa ni awon eroja kan ninu eje won, eyi ti won ti ko lati ara iya won ninu oyun. Eyi ko si fi han wipe won ni kokoro yi.

Ni awon akoko bayi, a ni lati se ayewo yi lehin igba die, tabi ki a se iru awon ayewo miran.

**Ki ni itumo esi ayewo yi?**

Ti esi ayewo yi ba je BEE NI, o fi han wipe eniyan naa ti ni kokoro yi lara.

Ti esi ba je BEE KO, o fi han wipe iru eniyan bee ko ti se ibapade kokoro HIV ni iwon osu meji tabi meta seyin.

**Tani a o so esi ayewo yi fun?**

Ko si eni ti o le mo esi ayewo yi, afi eni ti eniyan ti o se ayewo naa ba fe so fun.

**Ki ni yio sele leyin ti a ba ti se ayewo yi tan?**

Lehin ti a ba ti gba esi ayewo yi, awon agbani ni iyanju yio so itumo esi yi fun ni, ati awon koko oro inu esi naa. Igbese yi se koko ninu sise ayewo yi. Awon agbani ni iyanju yio fi ye iru eniyan bee ohun ti a ni lati se ki aye eniyan bee le te si iwaju. Bi o ti wu ki o ri, a ni lati fun eniyan ni amoran lori ibalopo ati awon ohun miran eyi to le mu ki eniyan se ibapade kokoro HIV.

**Kini a le se ni igba ti esi ayewo ba je BEE NI?**

Ni igba ti kokoro HIV ba ti wo inu ara eniyan, awon ona si wa ti iru eniyan bee fi le maa gbe ni alaafia. O sese ki iru eiyan bee ni lati lo awon oogun kan lati gbogun ti kokoro yi. Kokoro HIV tun le se okunfa awon aarun miran bi iko ifere. Awon onisegun oyibo yio ran eniyan lowo lati se itoju awon arun wonyi. Awon agbani ni iyanju yio tun so fun ni awon ibi ti a ti le ri iranwo gba.

O sese ki iru eni bee tun ni awon arun miran eyi ti a le ko lati ibi ibalopo, eyi ti o se koko ki a tun se ayewo fun.

O sese ki iru eniyan bee ni lati fi to awon eniyan kookan leti esi ayewo naa, paapaa awon ti o sese ki won ti ko arun yi lara iru eniyan bee. Iru awon wonyi le nilo lati se ayewo pelu.

Awon ti o ba ni oyun ni lati ri awon onisegun ti o le ran won lowo ki kokoro yi ma baa de ara omo won.

**Ki ni a ni lati se nigba ti esi ayewo ba je BEE KO?**

E yi fi han wipe iru eniyan bee ko se ibapade kokoro naa ni iwon osu meji si meta seyin. O dara ti a ba le tun ayewo yi si ni igba de igba. A o si gba iru eni bee ni iyanju bi a se le de ona kiko kokoro yi.

**Ona wo ni a le gba lati dena kiko arun HIV?**

Lilo roba idaabobo, sise ifeto somo bibi, ati sise ayewo fun awon arun ti a le ko lati ibi ibalopo ,le ran eniyan lowo lati dena kiko kokoro HIV. Awon agbani ni iyanju yi o so fun ni bi a se le je awon anfaani yi.

**Iru iranwo wo li eniyan nilo?**

Bi o ti wu ki o ri, awon eto wa lati se iranwo fun ni, ki a le ri wipe eniyan wa ni ifokan bale. Eto wa lati se iranwo fun awon ti okan won ni irewesi, riri owo lati lo, bi a o se toju awon omo, ile gbigbe, ati bebe lo. A ko ni fi awon asiri yi han enikaeni afi awon ti eniyan bee ba fe ki a fi han.

**Awon wo lo ye ki o se ayewo arun HIV yi?**

A ro awon iru eniyan bayi lati se ayewo:

1. eni ti o ro wipe ohun ti se ibapade kokoro HIV.
2.eni ti o ba ti ni arun ti a le ko lati ibi ibalopo.
3. awon aboyun.
4. eni ti o ba ti ya abere lo ri, lati fi gun ara.
5.awon onise isegun, ti o n sise pelu eje awon eniyan.
6. eni ti ko ba le jeri eniyan ti o n ba ni ibalopo.
7. eni ti o ba fe ni idaniloju aye ti o wa.

Translated into Yoruba Language by:
Dr. ADEOTI, Abolaji.
Pretoria, South Africa.
30/Nov/2007.